**Irohin Yoruba**

NO. 824. MARCH 22 — MARCH 28, 1961 KOBO MEJI (2D)

**Lakaye Ọrọ**

Ṣugbọn iwọ, nigbati iwọ ba ngbawẹ, fi ororo kun ori rẹ, ki o si bọju rẹ. Ki iwọ ki o maṣe farahan fun enia pe, iwọ ngbawẹ, bikoṣe fun Baba rẹ ti mbẹ ni ikọkọ; Baba rẹ ti o si riran ni ikọkọ yio san an fun ọ ni gbangba (Matteu 6; 14-18).




Dara fun Ẹjẹ Ọmọde, Agba ati Aboyun

O wa fun tita kakiri Ile-egbogi

# ỌJỌ MEJI NI AWỌN IMALE EKO KIRUN ITUNU AWẸ



*Aworan oke yi ni ti awọn Musulumi Eko nigbati nwọn nkirun Itunu Awẹ ni Ọbalende. Lẹhinti nwọn ti kirun tan, ti nwọn si ṣe adura ni onikaluku ba lọ si aye wọn nibiti nwọn ti tun to lati ma a lọ sile wọn pẹlu orin iyin fun Ọlọrun (Wo oju ewe kẹrindinlogun fun irohin)*

# ITAN KONGO (4)

PATAKI ohun ti o da rogbodiyan sile ni ilu Kongo ni igbati Ọgbẹni Kasavubu bẹrẹ ija arumọjẹ kan labẹnu.

Ohun ti o ṣe nipe, o fa ọdọmọkunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Bonboko ẹni ọdun mẹtadilogbọn bọdi nigbati



MOBUTU

ọmọkunrin na wa ni aye ipo Minista Alamojuto Eto awọn Ilu Ajoji (Minista of Foreign Affairs). O si kọ ọ pe ki o ko gbogbo owo ti o wa ninu Ile-Iṣura Ijọba Kongo (Congo Government Treasury) pamọ.

### IDARUDAPỌ

Lẹhin ti Bondoko ti ko owo Ile-iṣura Ijọba na pamọ tan, ti awọn alamojuto Ile-iṣura mọ, ni Ọgbẹni Lumumba ba figbeta wipe bawo ni owo ti ṣe tan ninu Ile-iṣura na? Asẹhinwa-asẹhinbọ, Lumumba ati gbogbo awọn isọngbe rẹ si parapọ, nwọn yọ Bonboko kuro ninu ẹgbẹ oṣelu wọn. Gbara ti eyi ṣẹlẹ ni idarudapọ ba bẹ silẹ larin wọn.

Lumumba fẹ fi Bobutu jẹ olori-ogun, ṣugbọn amiokun ẹyokanṣoṣo ni Mobutu ti gba ninu iṣẹ Sọja, nitorina, aye yi ko tete bọsi i fun Mobutu nigbati o jẹwipe Ọgbẹni Victor Lundule Ṣaji-Mejọ awọn Ṣọja (Regimental Sergeant Major) ti iṣe ọmọ ilu Lumumba paapa, amiokun Ṣọja meji pere ni o gba.

### KO SI ITẸLỌRUN

Nitoripe ọrọ yi ko tẹ Lundule lọrun. Lumumba bẹ ẹ, o si ṣe arọwa fun lọpọlọpọ. Lundule si gba ẹbẹ na, o fi ọwọ wọnu, o si gba pe ki o fi Mobutu jẹ Ọga sibẹ.

Sibẹsibẹ na, ọrọ yi ko yanju, nitoripe Ọgbẹni Deoboussiere, Olori-ogun Kongo (Chief Congolese Army of Staff) ko jẹ gba igbakugba.

Lumumba si kọ Mobutu pe ki o da ija silẹ, ṣugbọn nigbati ija na pari tan, ni Deoboussi : ba bẹrẹsi binu, o sọ fun awọn ara ilẹ Kongo wipe, bi nwọn ba ro wipe nwọn ti gba Ominira Ijọba, irọ patapata ni nwọn npa tan ara wọn jẹ.

O sọ fun wọn pe abẹ Ijọba Belgium gan an ni nwọn si wa ati wipe, iya si mbọ wa jẹ wọn dada fun nkan ti nwọn ṣe yẹn.

Ọrọ yi bi Lumumba ninu pupọ nigbati o gbọ o, o si binu yọ Deoboussiere, olori-

**(Lati ọwọ T. Ajayi Thomas, Eko)**

ogun na kuro lẹnu iṣẹ.

### MOBUTU DI ỌGA

Gbara ti Lumumba ti jaja yẹju Deoboussiere kuro ninu Ẹgbẹ Ọmọ-ogun tan, ni o ba fi Mobutu jẹ oye olori awọn ṣọja (Colonel). Ṣugbọn Deoboussiere ko dakẹ lasan si ọran yi, o yọ kẹlẹkẹlẹ fi iwe ẹsun kan ranṣẹ si Ijọba Belgium o si sọ wipe, lori nkan ti Mobutu ṣe yi, iya nilati jẹ ẹ pẹlu gbogbo ẹlẹgbẹ rẹ.

O si fi ọgbọ-ọgbọn tan Lundule pe ki o fowosi iwe na. Lẹsẹkẹsẹ ti Lundule si ti fi ọwọ si iwe na tan ni ija nla ba bẹrẹ.

Lati igbati Akoso Ijọba ilu Belgian Congo ti wa ni abẹ akoso awọn Oyinbo ilu Belgium, ni nwọn ti pin ilẹ awọn ohun-iṣura ati okuta iyebiye ti o wa ni Ilẹ-Koto Iṣura Ijọba Belgian Congo, larin awọn Onisọwo Ijọba ilu wọn ati awọn ilu Ajoji ti o wa pẹlu wọn ni Kongo.

### ILẸ OHUN IṢURA

Awọn ilẹ ohun-iṣura okuta iyebiye ati ti Uranium ti nwọn fi nṣe Bọmbu oloro ti o wa ni koto-ilẹ Katanga ati awọn ilu mi-



KASAVUBU

★ ★ ★

ran bẹ ẹ bẹ ẹ lọ ni nwọn pin larin awọn ilu nlanla marun (shareholders) bi Amerika, Gẹẹsi, Faranse, Afirika ti Iha Ariwa South Africa) ati Iha Ariwa Rhodesia bayi:—

Nwọn pin ida mẹrindilogbọn ninu ọgọrun (26%) fun ilu Amẹrika, ida-mẹdọgbọn ninu ọgọrun (25%) fun Gẹẹsi, ida-mẹdọgbọn ninu ọgọrun fun Faranse, ida-mẹwa ninu ọgọrun (10%) fun Afirika ti Iha Ariwa (South Africa), ida-mẹwa ninu ọgọrun (10%) fun Iha Ariwa Rhodesia (Southern Rhodesia).

### ILE OWO FỌ

Nigbati ija wa bẹ silẹ larin wọn ni Ile-Owo (Bank) ba fọ, ko si owo mọ rara, koda ko tilẹ si onjẹ paapa lati fi bọ awọn ọmọ-ogun mọ, nitoripe Bonboko ti ko gbogbo owo ti o wa ninu Ile-owo (Treasury) jẹ patapata.

Awọn ilu ti nwọn si ri ipin owo ati ti ohun-Iṣura pupọju pin ni ilẹ Kongo bẹrẹsi fi owo ati ọpọlọpọ ohun eelo ran Mobutu lọwọ.

Nigbati ọran na wa ri bayi, ti Lumumba ko ni owo lọwọ ti o le san fun awọn ọmọ-ogun, ni awọn ọmọ-ogun ba kẹhin si i, nwọn ko si jagun fun un



TSHOMBE

★ ★ ★

mọ, nwọn tẹle Mobutu, wọn si jagun fun un.

### KATANGA

Gbogbo nkan ti Mobutu ba sọ wipe ki nwọn ṣe ni nwọn ṣe. Nigbati Mobutu si ri i wipe ẹsẹ on ti ranlẹ tan, ti apa on si ka gbogbo ohunkohun ti on ba fẹ, ni o ba lọ dapọ mọ Kasavubu ati Tshombe.

Nigbati o si di ọjọ kẹtadilogbọn oṣu kẹfa ọdun 1960. (27/6/60) ni Tshombe ba sọ wipe, ilu ti on, Katanga ti yọ kuro patapata ninu Ijọba ilẹ Kongo.

O ni awọn ti da wa funra ara awọn gedegbe o si sọ orukọ Ijọba tiwọn ti nwọn ya sọtọ na ni "Breakaway Katanga Province".

Nigbati o si tun di ọsẹ kini ninu oṣu keje ọdun 1960 ni Ọgbẹni Kaloiyi ba tun sọ wipe ilu t'on na, "Kasai" ti yọ kuro ninu Ijọba Kongo, awọn na ti daduro gedegbe.

Bayi ni idarudapọ ba de patapata. Inu awọn ilu ajeji si ndun si ọrọ yi nipa iru aye kẹhinsorogun ti awọn enia ilu Kongo wa si ara wọn yi.

Nwọn bẹrẹsi finna mọ nkan nidi kikankikan, nwọn si nko ọpọlọpọ owo fun Mobutu, Kasavubu ati Thombe.

**(KOI TI PARI O)**



# Ọlọwọ Ọwọ yọ ayọ ogun ọdun lori oye

ỌWỌ.

**GBOGBO awọn ọmọ Ọwọ nile ati l'oko lo wa ba Ọba Alaiyeluwa Ọlọla Ọlatẹru Ọlagbegi Keji, Ọlọwọ Ọwọ yọ ayọ ogun ọdun ti o ti gba ade, ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kejila oṣu yi.**

Lati alẹ ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kọkanla oṣu yi ni awọn ero ti nwọ wa sinu Afin Ọlọwọ, ti gbogbo igun mẹrẹrin ilu si nrọ kẹkẹ fun imurasilẹ de ọjọ keji. Ogunlọgọ enia lo wa lati Eko, Ibadan, Abẹokuta, Ijẹbu, Oshogbo ati lati ilu miran ni ọna Oke Ọya.

Nigbati o si ti di fẹrẹ kilẹmọ ọjọ ajọyọ na, ni fere ti ndun lati Afin, ti onikaluku si ngmura lati lọ ṣe ẹyẹ fun Ọba wọn.

Ninu iwe-ikini-ku oriire ti awọn ọmọ ilu Ọwọ fun un. Nwọn sọ pe; Ọba Alaiyeluwa Ọlọwọ Ọwọ jẹ alakikanju ati onisuru Ọba, nwọn ni igba rẹ si tu gbogbo awọn ara ilu lara.

Nwọn ni nipa akikanju rẹ na ni o fi tun ilu Ọwọ ṣe depo ti ilu na fi le fi ẹsẹ wọn ẹsẹ pẹlu awọn ilu ọlaju miran ni Naijiria. Nwọn si tun ṣe ileri pe awọn yio wa ni irẹpọ pẹlu Ọba Ọlọwọ lati ṣiṣẹ fun idagbasoke ati ire ilu wọn.

Ninu esi rẹ si iwe ikini ti awọn ara ilu fun un, Ọlọwọ dupẹ ni iwọn iba ṣoki lọwọ awọn ọmọ ilu rẹ fun ọrọ iwuri ati aponle ti nwọn sọ nipa rẹ. O ni nigbati ẹmi on ba si mbẹ on yio ma a wa ire ilu on ati ti awọn enia inu rẹ.

Ọba Alaiyeluwa Ọlọla Ọlatẹru Ọlagbeji Keji jọba ni odun 1941. Ṣiwaju ki o to jọba, o ti ṣiṣẹ olukọni ri, o si jẹ alakikanju enia. O tun jẹ oninure ati onisuru ẹda pẹlu. Gbogbo iwa daradara wọnyi lo si gbe e nigbati o de ori oye na lati bi ogun ọdun sẹhin.

Awọn ara ilu rẹ n'ifẹ rẹ. Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun mbu ọwọ fun un. Ijọba Gẹẹsi ati Apapọ Ijọba Naijiria paapa si yẹ ẹ si pẹlu. Nipa pe awọn Ijọba wọnyi mọ riri rẹ ni nwọn ti ṣe da a lọla oye ti Ọlọlajulọ Ọba-birin Gẹẹsi Elizabeth Keji fun un ni ọdun bi melo kan sẹhin.

Aṣeyi ṣamọdun o, Kabiyesi Ọba.



Oba Alaiyeluwa Ọlọla Ọlatẹru Ọlagbeji Keji Ọlọwọ Ọwọ.


## Gbọn aisan awọ-ara rẹ nu loru ọjọ kan



**Egbogi titun ti nwọn ṣẹṣẹ fi ọgbọn ijinlẹ wari bẹrẹ si fi opin si awọn aisan ekuru, rorẹ, lapalapa, ogodo, ekusa ati iṣaka-ẹsẹ loojọ—Onṣiṣẹ lọ nigbati o ba sun.**

NIXODERM jẹ egbogi apolu pataki olorisi oogun meje ti o jẹ ipara funfun ti o nyara ba awọn aleebu-ara ja bi Ekuru, Rore, Arasisu Lapalapa, Ogodo, Ela-oloronta, Oowo-imu, awọ-oriṣiṣi kokoro jerun-jerun ati Iṣaka-ẹsẹ. NIXODERM nda ni kiakia a si da ara-bibun duro larin iṣẹju meje. O le ri agbayanu iyipada lẹhin ọjọ [illegible] ti o ba lo o. Ṣa fi pa oju ibiti o ndun o ni awọ-ara ki o to lọ sun. Tiripẹpẹ ni yio dimo ibẹ gẹgẹbi ibọwọ afẹeri a si ma a ṣiṣẹ nigbati iwọ ba nsun. Nigbati o ba dide ni aro ọjọ keji, wa ri i pe awọ-ara rẹ ti mọkadara, a di akọtun, a jọlọ, a si ṣe mulọmulọ. Larin [illegible] die, enu yio ya awọn ọrẹ rẹ si iyipada na. Maṣe jẹki idaamu mu ọ padanu awọn ọrẹ rẹ nipa pe o ni awọ-ara buruku. Lo NIXODERM l'oni ki o si ri i bi gbajumọ rẹ yio ti tabọ ga si. NIXODERM ntete yara ṣiṣẹ nitoripe o mba awọn oniruru kokoro ti o nda awọ-ara laamu ja, a si pa gbogbo wọn. Ra NIXODERM ni ile-egbogi adugbo rẹ loni. O gbọdọ ni itẹlọrun pẹlu rẹ, bibẹko a ti ṣeleri lati da owo rẹ pada.

**NIXODERM**






**FERESE ATATA NI NITORI:**

Ayọ t'o gbe jingi rẹ duro jẹ k'o rọrun lati ṣi.
Ọda t'o ba fẹ l'o le fi kun u.
Oriṣi meji l'opo rẹ: onirin ati ayọ. Onirin lagbara; alayọ ndan yọyọ.
O ṣe ṣi diẹ; o ṣe ṣi pupọ fun atẹgun
O rọrun lati fi kọ'le.
Gbogbo ẹni t'o lo o ni Iwọ Orun Afrika jẹri pe o dara

**NACO SUN SASH**

**FERESE ALATẸGUN TI A ṢE NI NIGERIA**

**VIVIAN, YOUNGER & BOND LTD.**

LAGOS IBADAN PORT HARCOURT KANO KADUNA ENUGU.




# Ẹgb
# ki

ILE Iṣẹ irohin Ẹgbẹ Afẹ fere (Action Group B ṣe ikede kan ni ọjọ Ọjọ reau of Information) l'E ti iṣe ọjọ kerindinlog oṣu yi nipa gẹgẹbi Alako Apapọ Ijọba Naijiria, A haji Ọlọla Abubakar T fawa Balewa ti ṣe gbiya ju si nibi ipade awọn Al koso Ijọba Orilẹ-ede nwọn ṣe nilu Londonu.



OLOYE S. L. AKINTỌ

Ikede na yin Ọlọla Ab bakar fun aye to lo nin ipade na gẹgẹbi ọrọ ti o nigbati nwọn nṣe ipinn lori ọrọ ilu "South Africa ọkan ninu awọn ilu ti mb wọn ṣe ipade na.

Ikede na tun kan saa si Ọlọla Abubakar Tafaw Balewa fun igboiya rẹ ni nu ipade nla yi, o si tu ran gbogbo enia leti pe ey ni ẹkeji ti Ọlọla Abubaka

## Iṣile Ọnawus



# …e Afẹnifẹre … Balewa

…nfaramọ ifẹ ilu gẹgẹbi Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria.

Igba ekini ni gbigba ti Ọlọla Abubakar gba lati fun Ijọba Russia laye ki o ni Aṣoju rẹ ni Naijiria, ki o si ṣi Ile Aṣoju na si ilu. Ẹgbẹ Afẹnifẹre ki i pupọ fun eyi. Ẹgbẹ na sọ pe ṣugbọn iṣẹ ṣi ku pupọ fun Ọlọla Abubakar Tafawa Balewa lati ṣe. O ni pataki lo ẹrọ Redio ni bonkẹlẹ ni ilu yi.

Ni ipari, Ẹgbẹ Afẹnifẹre sọ pe on ni ireti pe ninu gbogbo eto ki eto ti o ba jẹ mọ ti ilu Naijiria pẹlu ilu okeere, Ọlọla Abubakar ki yio jẹ ki Dọkita Kwame Nkrumah Alakoso Ijọba ilu Ghana gba aye iwaju lọwọ on mọ.



Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ OLOYE AYỌ ROṢIJI

ninu awọn iṣẹ na si ni bi yio ti ṣe gbiyanju ki o bọ ajaga ilu Gẹẹsi kuro lọrun Naijiria.

Ẹgbẹ na ni akoko iṣẹ pataki na ni ki Ọlọla Abubakar gẹgẹbi Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria, ri pe on pa iwe adehun to wa larin Naijiria ati ilu Gẹẹsi rẹ nipa eto aabo ogun, ati pe ki o si sa gbogbo agbara rẹ ki Naijiria o fi yọ kuro ninu ẹgbẹ NATO eyiti o ti ba ṣe adehun lati ma a…

**Irohin ko to afọjuba ni ti aṣeyẹ inawo ti ile ti Iyaafin C. O. Ọnawusi ṣi si Surulere. Ogunlọgọ awọn enia lo wa sibi iṣile na. Awọn ẹgbẹ Iyaafin na si ṣe bẹbẹ lọjọ na Bi nwọn ti njo, ni nwọn nyọ ti nwọn si ngnawo. Aworan isalẹ yi ni ti igbati Iyaafin Ọnawusi na njo pẹlu awọn ọrẹ rẹ ninu aṣọ ẹbi ti nwọn da fun ti iṣile na.**

## …dun



# Babalọla jẹ oye olori onilu Ẹgba

ABẸOKUTA.

**ẸSẸ awọn ọmọ Ijaiye pataki-pataki lati Eko, Ibadan, Ilaro, Agege, Otta ati gbogbo agbegbe Abẹokuta ni o pe sibi aṣeyẹ ifinijoye ti Ọgbẹni Kelani Babalọla, ti nwọn fi jẹ oye Olori Onilu Ẹgba ni ọjọ karun oṣu ti o kọja yi ni ile olori onilu ologbe Tijuku Abẹokuta.**

**Oye yi sọ Ọgbẹni Babalọla di onilu Ọba.**

Ọgbẹni Gbadamọsi Okẹ Otun Olori onilu gbogbo Ẹgba ni o ṣe eto oye ọjọ na. Oloye Adewuyi Are, Ibadan, Abẹokuta ni o fi ewe oye le Oloye titun na lori.

Lẹhin eyi ni Oloye titun na ati awọn ẹbi rẹ pẹlu ogunlọgọ awọn onilu Abẹokuta ba a de ile rẹ ni Agbo-ile ADAN, Ijaiye Abẹokuta. Nibẹ ni o si ti fi jijẹ ati mimu tẹ awọn alabaṣeyẹ ọjọ na lọrun.

Oloye Babalọla ni o ti ma a nlu ilu fun awọn Ọba Ẹgba lati ọdun pupọ sẹhin, awọn ọba ti o ti lu ilu fun ni Ologbe Gbadebọ Alake, Ṣokunbi Karunwi Oshilẹ ati Ọba Alaiyeluwa Ọladapọ Ademọla Keji, Alake Abẹokuta.

Ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu ti o kọja yi ni Oloye titun na ati ogunlọgọ awọn enia pẹlu ijo ati **ilu lọ si afin Ake lati lọ** yilẹ fun Ọba Alaiyeluwa Ademọla Keji Alake Abẹokuta.

Ọba Alake si gba a towọtẹṣẹ, o ta a lọrẹ, o si ṣadura fun pe ki oye ko mọ ọ lori.



OLOYE KELANI BABALOLA



**ỌRỌ AKEWI : Lati ọwọ ỌMỌ-ỌBA AKIBU ALARAPE, IBADAN**

# ALUBARIKA L'OJU (9)

AJINDE-ARA yio ma a jẹ fun nyin o, Olotu iwe "Irohin Yoruba". Mo ro wipe ẹnyin onkawe wa ko ni gbagbe wipe ibiti a ba ọrọ wa de ni wipe, awọn ogboni mẹtẹta na ba ọna tiwọn lọ nigbati ọwọ wọn ti ba ẹgbẹrun pọnun na.

Gẹgẹbi ẹnyin na yio si ti mọ, nṣe ni ọrọ na dabi ẹniwipe nwọn ti sọ fun ara wọn, nitoripe ọpọlọpọ ni irufẹ awọn enia bawọnyi ti nwọn nwọ wa si ile "Ibukun-Oluwa-Lo Ju" ni ojojumọ; ti onikaluku wọn si ngba owo nlanla bayi lọwọ iyawo rẹ pẹlu awọn ọmọ rẹ keekeeke na.

To bẹ ẹ, ti o fi jẹwipe, gbogbo owo na si fi tan kẹdẹrẹ. Ere ni, awada ni, ati gbogbo ile ati awọn oko nlanla, gbogbo rẹ tan patapata porongodo afi ile kanna ti nwọn wa ninu rẹ ni o ṣẹku fun wọn, o si tun ṣẹku ọkọ oju-omi kekere kanṣoṣo.

### AKIYESI

Ṣugbọn sibẹsibẹ na ẹwẹ, awọn janduku enia wọnyi si nwa lati bere nkan ti ko si lọwọ iyawo yi ati awọn ọmọ rẹ bakanna. Bayi ni Mofoluwaṣọ ti o jẹ akọbi obinrin na nṣe akiyesi bi gbogbo nkan na ti ṣe nlọ.

Mofoluwaṣọ wa kesi iya rẹ ni owurọ ọjọ kan bayi, osi sọ fun iya rẹ wipe: "nisisiyi ni mo ṣe akiyesi nipa gẹgẹbi ọrọ wa ti nlọ yi, ti mo si ri i daju wipe bi nkan na ba nlọ bayi laiṣe ani-ani, ibiti nkan na yio yọri si ko ni dara.

"Bẹ ẹ si ni, ako ni fẹ ki a ru ofin tabi ikilọ ti baba wa ti ṣe silẹ fun wa wipe awa ko gbọdọ fi ẹnu wa ṣẹ epe nipa ohunkohun bayiowu ki o tile ri.

### IMỌRAN

Njẹ nisisiyi, gẹgẹbi ero temi, bi ẹ ko ba ni ka ero mi na si ero ọmọde, ko si ohun ti o ṣẹku fun wa mọ nisisyi ti a le ṣe bikoṣe wipe ki a jade kuro ni ilu yi loni gan an, bi bẹ ẹ si kọ ọrọ na yio tubọ buru si i ni igbẹhin."

Iya rẹ si fi tayọtayọ gba imọran na pẹlu omije ẹkun loju. O si ṣe adura fun ọmọ rẹ na daradara. Lẹhin eyi ni iya rẹ wa sọ fun un wipe, otitọ ni imọran yi dara pupọ, atipe, o tilẹ ba ero ọkan ti on paapa mu.

"Ṣugbọn ti a ba tilẹ sọ wipe a fe jade kuro ni ilu yi nisisiyi, bawo ni a o ti ṣe nkan na si nwọn igbati o jẹwipe ko si owo kankan lọwọ wa ti a le fi wọ ọkọ, ti o si tun jẹwipe awọn aburo rẹ mejeji yoku ko le rin to bẹ ẹ, tabi a ha le fi wọn silẹ lọ bi?"

### IRINAJO

Mofoluwaṣọ si dahun, o ni: "nitootọ, ko si owo lọwọ wa ṣugbọn sibẹsibẹ na, ṣe awa na sa ni ọkọ oju-omi



AKIBU ALARAPE

kekere kan ni Ebute? Nipa bẹ ẹ, ọkọ na le wulo fun wa nipa irin-ajo wa na laiṣẹṣẹ tun ni na wa ni owo kankan mọ."

Laifa ọrọ na gun lọ titi mọ, bayi ni awọn enia na palẹmọ lẹsẹkẹsẹ ti nwọn si kọri si ọna Ebute. Awọn enia mẹrẹrin na si bọsi inu ọkọ na pẹlu Ogo Ọlọrun, laini ero wipe ibikan bayi gan an ni awọn nlọ.

Ọkọ wọn si gbera ni ebute, wọn si mba irin-ajo wọn na lọ titi ti ilẹ ọjọ na fi ṣu larin agbami, ọkọ na si nlọ rere laidaraduro.

Nigbati nwọn rin irin bi ọjọ mẹta loju omi laikan ilu kakan tabi ileto rara, aiya wọn bẹrẹsi ija dẹdie, paapa julọ, awọn ọmọde meji ti o mbẹ larin wọn.

### ATẸGUN NLA

To bẹ ẹ, ti awọn ọmọ na fi mbere lọwọ iya wọn wipe nibo ni a wa nlọ lati iye ọjọ yi, ti awọn ko si ti i le kan ilu kankan tabi ileto kan bikoṣe kiki omi lọtun-losi, tabi ọkọ wa ha ti ṣina ni bi?"

Lẹnu ibiti nwọn ti nsọrọ yi lọwọ ni atẹgun nla kan ti bẹrẹsi i fẹ, atẹgun na si lagbara to bẹ ẹ gẹ ẹ ti enikẹni ko fi le sọrọ si ara wọn mọ.

Atẹgun nla na si bẹrẹsi gbe ọkọ wọn sure lọ loju omi, to bẹ ẹ ti o fi jẹwipe, larin iṣẹju marun ni ọkọ na fi nrin irin odidi ọjọ kan loju omi.

Nigbati atẹgun yi fẹ to nkan bi wakati mẹjọ o tun bẹrẹsi lagbara si i ju ti atẹhinwa lọ, lojiji ni ọkọ na si la si meji lọgbọọgba pẹrẹ lẹkanna. Mofoluwaṣọ ati iya rẹ wa ni apakan, awọn ọmọde keekeeke meji yoku si wa ni apakeji akilaya ọkọ ti o fọ na.

Lẹsẹkẹsẹ na ni omu gbe apakan ọkọ na gba ọna apa ọtun, o si gbe apakeji gba ọna apa osi ti awọn enia apa mejeji na si nwo ara wọn lọ lọkankan titi bi omi ti ngbe ọkọ wọn lọ, titi bẹ ẹ ti nwọn ko si fi ri ara wọn mọ loju omi.

Bi omi ti ngbe apa kini ati apakeji akufọ ọkọ wọn lọ yi, bẹ ẹ ni atẹgun na sa tubọ nle si i ti o si ngni agbara si i bakanna.

Nigbati o di nkan bi wakati mẹrin lẹhin eyi, nṣe ni apakan ọkọ ti Mofoluwaṣọ ati iya rẹ wa ninu rẹ tun la si meji pẹrẹgẹdẹ.

Olotu, ki a tun fi rere pade ni ọjọ miran ọjọ rere o.

O digba.

**(KOI TI PARI)**




# EWO NI IRỌ, EWO NI OTITỌ?

## (Lati ọwọ Ajakaiye - Ogun Wasimi)

**OLOTU, ẹ jọwọ gba mi laye diẹ ninu iwe "Irohin Yoruba" nyin akọmọlọgbọn lati bere ibere kan wipe, ninu ọrọ awọn meji kan ti o tako ara wọn yi. Ewo ni irọ, ewo si ni otitọ?**

Ekini:—Ninu iwe "Irohin Yoruba" ti o jade ni ọjọ 28-4-58, a ri aworan alagba obirin kan ti o pe oruko ara ni Elizabeth Ọmọlade ni oju ewe kini iwe na, ti o mu aworan ẹiyẹ kan dani, ti o si sọ wipe on pọ ẹiyẹ-ajẹ na ninu Ṣọọṣi Aladura kan, "Christ Apostolic Mission" ni Mushin.

Ti ki i ba ṣe pe ọdọ mi nikan ni iwe "Irohin Yoruba" duro ni ọjọ na, mo ro wipe awọn onka ati onkọ iwe Irohin Yoruba ni yio ri aworan obirin na pẹlu nkan ti o mu dani gẹgẹbi ẹiyẹ. Nitorina iyẹn fi han pe, ẸIYẸ NI AJẸ. Ẹni ti o ṣe adura fun un ti o fi pọ ẹiyẹ-ajẹ na ni Evangelist J. A. Agbọna.

**AWORAN LYDIA**

Lẹhinna, ekeji ni ti aworan Omida Lydia Ọlatundun, ọmọ Ọgbẹni Jacob Abọdunde, ni ilu Gbọngan ati aworan Alufa rẹ S. O. Ọmọnubi (Doctor de Love), ti o jade ni oju ewe kini ati ikẹtala iwe "Irohin Yoruba" ti ọjọ 1-7/2/61, ti ọmọbirin na si sọ ninu ọro rẹ pe on ti nṣe Ajẹ lati ọdun merin sẹhin, ṣugbọn Alufa yi si ti ṣe adura gbigbona le on lori, on si ti fi ẹgbẹ OṢO ati AJẸ silẹ, on ko se ẹgbẹ okunkun mọ, on si ti di ọmọ Ẹgbẹ Aladura.

Gẹgẹbi ẹnyin onkawe "Irohin Yoruba" na ti mọ oro rẹ na ti pọ ju ohun ti mo le ma a to lẹsẹ-ẹsẹ lọ, nitoripe, iwe yi ko le gba laye to bẹ ẹ.

Nitorina ni nwọn si ṣe gbe ọrọ na wa si oju ewe kẹtala ati si oju ewe kẹrindilogun iwe "Irohin Yoruba" ti o jade ni ọjọ kẹjọ si ikẹrinla osu keji ọdun yi (8-14/2/61).

Ohun ti mo fẹ fi han ẹnyin onkawe mi yi ni wipe, ni oju ewe kẹtala iwe "Irohin Yoruba" ti 1-7/2/61 o fi ẹnu ba a pe: "AJẸ KI ṢE ẸIYẸ, ẸMI NI AJẸ, ỌLỌRUN NI AJẸ, ENIA SI NI AJẸ".

Iyoku ọrọ rẹ na tun jade ni oju ewe kẹjọ ati ikẹsan iwe "Irohin Yoruba" ti ọjọ 8/2/61, eyiti akọle rẹ lọ bayi:—"Mo ti di Aladura, nko ṣe Ajẹ mọ".

Ọmọbirin na tun wa tẹnumọ kikankikan pe, ko si nkan ti nje ẹiyẹ ajẹ, ajẹ ko ni ẹiyẹ rara, iṣẹ Ajẹ jẹ iṣẹ ibi pupọ, ki iṣe ẹiyẹ ni o ngbe enia kiri, Ẹmi ni."

**IRỌ ATI OTITỌ**

Se ẹ ngbọ-o jare, ẹnyin onkawe mi? Ibiti a nlọ ni a wa de yi o.

Ọmọlade sọ pe "Ẹiye ni Ajẹ" ninu iwe "Irohin Yoruba' ti ọjọ 28/4/58.

Omidan Lydia Ọlatundun sọ pe "Aje ki iṣe ẹiyẹ" ninu iwe Irohin Yoruba ti ọjọ 1/2/61 ati ti ọjọ 8-2-61.

Mo wa pe akiyesi ẹnyin onkawe si ọrọ awọn mẹjeji na pe, o tako ara wọn. Bi ọrọ enia meji ba si tako ara wọn bayi, bi nkan ba jẹ otitọ, ekeji nilati jẹ irọ (lie).

Nje, mo wa bere gẹgẹbi alaimọ lọwọ awọn ọjọgbọn onkawe "Irohin Yoruba" paapa lọwọ Olotu iwe "Irohin Yoruba" wipe: Ewo ni irọ, ewo ni otitọ o?

Oju ko fẹraku o. O digba diẹ na o.

* * *



Lydia Ọlaundun pẹlu ohun ija ajẹ rẹ

* *



Aworan yi ni ti ohun ija Lydia nlo nigbati o wa ninu ajọ awọn Ajẹ

## Idahun si ibere yi

**ANU ṣe ni pe Olotu iwe "Irohin Yoruba" ko le sọ ẹniti o npurọ tabi ẹniti o nsọ otitọ ninu ọrọ awọn obirin Ajẹ meji t'o yatọ si ara wọn yi, nitori Olotu iwe "Irohin Yoruba" ki iṣe Ajẹ, ko si le mọ nipa ohun ti awọn Ajẹ ngbemi ti nwọn fi ndi Ajẹ. Afi bi onibere na ba le kesi awọn onkawe "Irohin Yoruba" pe ti a ba ri ẹniti o le jẹwọ pe Ajẹ ni on ki o la ọrọ na ye wa bi Elizabeth Ọmọlade ni oba sọ otitọ ni, tabi Lydia Ọlatundun.**

**OLOTU.**

## Owe ilẹ Yoruba

ARUN ki i jẹ orukọ meji ju fi-mi-pamọ ki npa ọ lọ.

NWỌN ni: Aparo "eeṣe ti aṣọ rẹ fi pọn to bayi?" o ni bẹni: 'mo nfi ojumọ ọsan jẹ, mo nfi oru sun, mo si nfi abusun idaju owurọ tan ilẹ kurẹ-kurẹ, ni igbawo ni emi yio r'aye f'ọṣọ?'

A FI ejila ran mi ni idun l'Ajaṣẹ, bi a ko bari owo ẹni, a o ṣa ri idun ẹni.

AFINJU oge poponda ti i kun osun laiwẹ.

AGBA to ji ni kutukutu ka ori bọnu ni nle iṣẹ rẹ loro, kika ori bọnu ko tan ohun ti nṣe ni.




## IROHIN LATI OKE-OKUN ATI OKE-ỌYA

# Ọga Ọlọpa to ji ẹja fi pọnun mẹwa tanran

JOS.

**ADAJỌ Agba Kotu Kekere ni Jos ju Oyinbo Ọga Ọlọpa kan ti orukọ rẹ njẹ R. W. Clarke si ẹwọn oṣu kan, tabi ki o lọ fi pọnun mẹwa (£10) tanran ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kerinla oṣu yi, nitoripe o jẹbi ẹsun ti awọn ọlọpa fi sun pe o ji ẹja inu pangolo (salimọnu) ati pali wara (cheese) ti apapọ owo rẹ jẹ ṣile mẹrinla ni ile itaja "Kingsway Stores", Jos.**

Ọdaran yi jẹ ọga ọlọpa to wa fun iṣẹ ayẹwo awọn mọto ni ilu Jos. Ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi ni awọn ọlọpa kọkọ mu ọrọ rẹ wa si iwaju Adajọ Kekere. Nibẹ lo gbe ti sọ pe on ko jẹbi ẹsun ti awọn ọlọpa fi on sun.

Ni ọjọ na ni nwọn fi ẹjọ si ọjọ kẹtala oṣu yi niwaju Adajọ Agba, nwọn si gba iduro rẹ ni adọta pọnun (£50).

## Awọn ọlọṣa ṣa ọlọpa kan pa

KANO.

NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹrindinlogbon oṣu ti o koja yi ni ọlọpa Kano kan ti orukọ rẹ njẹ Nayaya Yakasai fẹnu ara rẹ sọ lori akete rẹ ki o to ku ni Ile-iwosan Kano (Kano City Hospital) fun awọn ọlọpa pe awọn ọlọṣa marun ti o jade lati mọto ayọkẹlẹ ni nwọn gbarajọ pọ ṣa on ni iṣakuṣa 'gbati o ri bi nwọn ti ṣe nrin irin-kurin ni agogo mẹta oru ti o si nṣe iwadi nipa irin wọn lọwọ wọn.

O ni ti on ba ri wọn, on ko le da wọn mọ ati mọto ayọkẹlẹ wọn pẹlu.

# *Awọn meje ku si ile ọlọti*

NAIROBI.

**LẸNULỌLỌYI ni awọn ọlọpa Nairobi ni Ila-Orun Afirika ṣe ikilọ fun awọn ti ongbe ilu Makadara pe ẹnikẹni ti o ba lọ mu ọti atowọda ni ile-ọti kan ni Makadara ki o tete yara lọ ri Dọkita fun itọju, nitoripe, majele wa ninu ọti na.**

Ohun ti o fa ikede ti awọn ọlọpa ṣe na ni pe awọn enia dudu meje ku lẹhin ti nwọn mu ọti tan, awọn mọkanla si tun wa ni ile-iwosan fun itọju.

Awọn ọlọpa ni awọn gba wipe ohun ti nwọn fi ṣe ọti na muro pupọ ati wipe awọn ti fi ninu ọti na ranṣẹ si Oniṣegun Ijọba (Government Chemist) fun ayẹwo.

Ọkunrin ti o ta ọti robirọbi na ati iyawo rẹ paapa mu ninu rẹ, awọn mejeji si ti jalaisi.

## Obirin kan bi ibẹrin

KAURA, ZARIA.

OBINRIN kan ti orukọ rẹ njẹ Iyaafin Ruti ọmọ ilu Kaura ileto kan ni agbegbe Zaria ni Ọlọrun ta lọrẹ ọmọ mẹrin lẹkanṣoṣo fun Ọgbẹni Make ọkọ rẹ.

Nigbati irohin kan nipa iṣẹ Ọlọrun yi, gbogbo enia lọ lọ si ibiti obirin na bi awọn ibẹrin na si lati lọ ki i.

## *Eze pokunso*

UMUABI-UDI.

LẸNULỌLỌYI ni babalawo kan ti orukọ rẹ njẹ Eze Eneh ẹni ọdun mọkanleladọta (51) pokunso ni Oju'bọ Oriṣa kan ni ilu Umuabi ni agbegbe Udi, ni Ipinlẹ Ila-Orun Naijiria. Lọwọ iku ojiji, Oluwa rere gba wa.


Mu **OVALTINE** *lojojumọ!*



Mu OVALTINE larọ fun agbara jalẹ gbogbo ọjọ.

Mu OVALTINE sun lalẹ lati fi ara rẹ si eto nigbati o ba sun.



**OVALTINE** — Onjẹ Atata — ti o jẹ nkan Mimu

